**LAKAYE ORO**

OJU Oluwa mbẹ lara awọn olododo eti rẹ si ṣi si igbe wọn Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe buburu lati ke iranti wọn kuro lori ile

Awọn olododo nke Oluwa si gbọ, o si yọ wọn jade kuro ninu ise wọn gbogbo.

# Irohin Yoruba

NO. 775 — APRIL 13 — APRIL 19, 1960 — Kobo Meji (2D.)

**OWE**

A NJUWỌN ko ṣe wi tejo tia ilara ko tan nore

Agbalagba ti yio te ile tutu yio da omi siwaju Igba ki i to lo bi orere aiye ki i to lo bi opa ibon.

# IWINLẸ ODO FẸRẸ GBE OBIRIN KAN LỌ, O SỌỌ DI AABỌ ENIA.

AIYESAN LẸBA ONDO.

NI owurọ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni obirin kan Emma Takurọ lọ si odo Yadi lati fo aṣọ ,o si ba obirin kan, Sabainah pade leti odo na, bi nwọn ti ki ara wọn tan, ti nwọn si bẹrẹsi ta oku ọrọ sọ, nigbati o ṣe, bi nwọn ti nsọrọ lọwọ ni Sabainah ko gbọ ohun obirin yi mọ, nigbati o bojuwo ibiti o wa ni o ri i pe kini kan nwọ ọ lọ si isalẹ omi; aṣẹ, Iwinlẹ-odo ni, ni o ba pa-kuru mọ Emma lati gba a lọwọ Iwinlẹ-odo na.

Bi Sabainah ti nfa a soke, bẹni Iwinlẹ-odo yi nfa a sodo, bẹni Emma paapa ntiraka lati bọ sọwọ Sabainah lati yọ ọ kuro lọwọ Iwinlẹ na.

Nigbati Sabainah ṣẹ nri i pe apa on ko ka a mọ, ni o ba figbeta pe: "gbogbo ara ebute, ẹgba ni o! a ri ẹng. mọ!! Ni gbogbo awọn ti o wa nitosi ba nsare bọ. Ṣugbọn ki nwọn to de ibẹ, nigbati Emma paapa mọ wipe o ṣẹ ndi oju iku, ni o wa ranti pe, bi ọran ba buru bayi, awọn Ilaṣẹ a ma a pe ogede (ọfọ) kan lati fi gba ara wọn silẹ, n io ba pe ogede (ẹfọ) na pe "Alubagha", nigbati Iwinlẹ yi gbọ ọfọ yi seti, ni ọwọ rẹ ba bẹrẹsi da, ti o si fi Emma silẹ. Gbogbo enia si ti pejọ

(Wo oju ewe ketala)

## IGBIMỌ IJỌBA IWỌ—ORUN PARI IPADE

£33,000,000 ni owo ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun yio na fun Iṣẹ Idagbasoke awọn ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun ni odunni.

IBADAN.

...Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun mu ipade ti nwọn ti bẹrẹsi ṣe lati ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu ti o koja yi wa si ipari di igbamiran.

Ki nwọn to pari ipade na, nwọn mu gbogbo eto bi nwọn yio ti ṣe na owo adọtalelẹgbẹti ṣe na owo adọtalelẹgbọjọ-ọkẹ ponun (£33,000,000) ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun yio na fun gbogbo ilu abẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun wa si opin, lẹhin na, ati atunṣe ofin ẹtọ Ijọba Ibilẹ lori bibu owo-ori pe, ko tun si lọwọ Ijọba Ibilẹ mọ, bikoṣe lọwọ Alaṣẹ kanṣoṣo

## Aro la awọn gende meji mọlẹ ni idi-Araba

IDI-ARABA, SURULERE.

OHUN iyanilẹnu ati ipanilẹrin ni o jẹ fun awọn ero iworan ati onilaja ti o pejọ si ikorita mẹta ni Idi Araba ni nkan bi agogo marun abọ irọlẹ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi nigbati nwọn ri bi arọ Hausa kan ti nlọ mọ awọn giripa ti nwọn nṣe iṣẹ 'Eyijẹ-eyi kojẹ' bi ejo ti o si ngbe wọn wọnlẹ bi ẹniti o ni ẹsẹ ti o fi nrin, nṣe ni ariwo nta ge e, eyi mu ki enia pọ nibẹ bi ọja.

Ohun ti o fa ija yi ni pe, arọ yi ni jẹjẹ on ni on nti ibiti on gbe ti nṣagbe bọ, bi on ti ni ki on sọda ni ikorita yi ni awọn ọkunrin mejeji yi pe on. On si ya lọdọ wọn. O ni nwọn sọ pe iyekiye ti on ba ni lọwọ ki on mu wa fi ta "eyijẹ-eyikojẹ" pe on yio si jẹ owo gọbọi. O ni on ko tilẹ yẹnu pada ti on fi da ṣile mejiabọ silẹ, o ni kia on ti jẹ ṣile mẹwa, nwọn si fun on ni ṣile mẹwa na. O ni nwọn sọ pe on ri aiye tabi

Wo oju ewe kẹrindinlogun

## E ku ipalẹmo Ọdun Ajinde



# Ọmọ Osagie ati aw̩n ẹgbẹ rẹ jẹbi

IBINI.

NI ọjọ Isẹgun ti ṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni Adajọ Agba Kotu kekere Ibini ṣe idajọ fun Oloye ọmọ Osogie. Akowe Igbimọ Minista Alamojuto Eto Inawo Apapọ Ijọba Na'jiria ati Olori Ẹgbẹ Otu Edo dapọmọ Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ati ẹnikeji rẹ. Daniel Oransaye pe ki ẹnikọọkan wọn lọ fiponun mọkanlelọgbọn ṣile mẹwa (£31. 10s.) tauran si Kotu tabi ẹwọn oṣu mẹrin-mẹrin, nitori ti nwọn jẹbi ẹsun ija ti awọn ọlọpa fi sun pe wọn ja.

Adajọ na si tun ṣe idajọ fun awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) mẹfa miran. awọn na ni:—Osadore Ovbiebo, Alfred Enaruna, Lawrence Okungbowa. Ericson Imafidon, Iduriase Eweka ati Daniel Emovon pe, ki ẹnikọọkan wọn lọ fi adọta ponun (£50) tanran si Kotu, tabi ki nwọn lọ si ẹwọn oṣu mẹfa-mẹfa nitoribẹ nwọn ba ariyan ja. nwọn si lu u lalubolẹ.

Ejọ ti ọlọpa ro mọ awọn ọdaran na lẹṣẹ ni pe nigbati Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) pe ipade ikede idibo wọle Igbimọ Apapọ Ijọba Na'jiria ti o kọja yi ni Abule Oza, ni ọjọ kọkanla oṣu kọkanla ọdun ti o kọja yi, ni gbogbo awọn ọdaran na ṣuru bo Ogbẹni Justin Igbinedion, ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o kuna ninu idibọ igba na, nwọn lu u bolẹ de aye ti o fi gbogbẹ lọpọlọpọ. ọjọ mẹta ni nwọn fi da a duro si ile-iwosan nitori ọgbẹ ti nwọn da si i lara.

# Lamidi gbe Amudatu ni iyawo

ZARIA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu kẹta ọdun yi ni Lamidi Ọladoṣu, ọmọ Ọffa gbe Amudatu ni iyawo alarinrin. Ẹsẹ awọn enia pataki pataki ni o pe ṣoṣo si ibi aṣeyẹ na, ọkọ iyawo si fi jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni awọn Ogbẹni Lamidi Eeso, Sule Ọlayimika, Lamidi Ṣango, Jubirila Ayanda ati Lasisi Olaiya.

Ki Oluwa fi ibukun si igbeyawo na ki O si fi ire kari o.

# Adajọ pa ipo Ṣorunkẹ rẹ ninu Apapọ Igbimo Ijọba

ABẸOKUTA.

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹdogbọn oṣu yi ni Ogbẹni W. T. Charles, Adajọ-Agba da ẹjọ ti Ogbẹni J. D. Odebunmi, ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre pe Oloye Emmanuel Shorunke, ọmọ Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) pe ki Kotu na ijoko rẹ re 'nu ajọ Igbimọ Apapọ Ijọba Na'jiria nitori onnaeru ni nwọn fi dibo fun un wọle Igbimọ na.

Adajọ na si da ẹjọ na pe otitọ ni ẹsun ti Ogbẹni Odẹbunmi fi Shorunkẹ sun pe, opolopo iwe idibo ti ko ni ootẹ Ijọba ninu ni nwọn ko mọ ibo fun Shorunkẹ ti ibo rẹ fi po ju t'on lọ.

Adajọ ni nitorina ki o lọ san ọgọjọ ponun o din ponun meji-abọ (£157, 10s.) owo irinṣẹ fun Ogbẹni Odẹbunmi ki nwọn ti tun ibo na di. Oloye F. R. A. Williams, Olori awọn agbẹjọro Ẹgbẹ Afẹnifẹre, ni o gba ẹnu ṣe fun Ogbẹni Odẹbunmi ninu ọran ẹjọ na.




# THAMES TRADER kan wa ti o yẹ fun ilo rẹ gan an.




AWỌN THAMES TRADER fere jẹ gbogbo oniruru iṣoro iṣe erukiko ni nwọn le ṣe tan. Nwọn ti ki gbogbo ara rẹ ni timutimu lati le ko awọn eru elegẹ. Ibi ijoko wiwa rẹ ni ile lori dada, o si tun le takiti eru ellẹ pẹlu irorun ni orisi ọna mẹta . . . gbogbo wọn ni o rorun lati tọju nwọn ko si njẹ epo pupọ. O si le yan eyiti o ba fẹ larin eyiti ti o nfi epo mọto ṣiṣẹ tabi eyiti o nlo awọn injinni diesel.

Awọn mọto FORD miran

15 — Jẹ kẹkẹ-akẹru ti o fuyẹ julọ ninu ẹwọ mọto TRADER

20 — O ni agbara eru kiko tọnun meji

30 — ẹwun ẹsẹ-kẹkẹ orisi meji

50 & 70 — O ni tanki epo oni galọnu mejidilogbọn ati injinni oni silinda mẹfa.

**J. ALLEN & Co. Ltd.** LAGOS, ABA BENIN, ENUGU, VICTORIA (S. CAMEROONS IBADAN, JOS, KANO, KADUNA, PORT HARCOURT, ZARIA.



Aworan yi ni ti awọn aşọfọ awọn enia meji-leladọrin ti awọn Ọlọpa Ijọba " South Africa " yinbọn pa laipẹ yi. Posi awọn meji leladọrun na ni nwọn to s'ilẹ yi nigbati nwọn nlo sin in wọn

# Ọwọ tẹ ọlọşa nibiti oti nmu bia

OWERRI.

OKUNRIN ọdaran kan Akujıobi Osuji alagbẹdẹ bamubamu ni Adajọ Kotu Kekere Owerri sọ si ẹwọn ọdun mẹta nitoripe o lọ ji saikulu ọmọ ọdun mẹwa kan gbe. Adajọ na si pasẹ pe ki o wa labẹ itọju awọn ọlọpa fun ọdun mẹta lẹhin ti o ba jade kuro ninu ẹwọn.

Bi ọran ẹjọ rẹ tiri wipe, nigbati ọdaran na pade ọmọkunrin kekere na l'ọna, o bi lere pe nibo lo nlọ? Ọmọ na si dahun pe on nwa awọn ti ntun kẹkẹ se lati b'on tun kẹkẹ on şe, nibẹ ni o ba ti tan ọmọ na pe on o mu lọ sibẹ, ni o ba fi ji keke na gbe mọ o lọwọ. Nibiti ọdaran na gbe ti ngmu bia ninu ile oti ni awọn ọlọpa ti ra a mu.

# Adajọ sọ awọn ole meji si ẹwọn ọdun metadin ogun

IBINI

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrindinlogbọn oşu ti o koja yi ni Adajọ Kotu Ibile Ijọba Ibini sẹ awọn ọlọsa meji Omoruyi Igbonowia si ẹwọn ọdun mẹjọ ati Williams Iyami si ẹwọn ọdun mẹsan nitori nwọn jebi esu ile fifọ ati ole jija ti awọn olopa fi wọn sun niwaju Adajọ.

# Ọjọ ibi Tonade dun

WASIMI.

NI ọjọ Aiku ti işe ọjọ ketala oşu kẹta ọdun yi ni Ọgbẹni Ayinde Tonade se ọjọ-ibi re o fi tijo ati mimu te gbogbo awọn enia ti o wa si ibi ase re na lorun. Aseye ojo-ibi na dun o larinrin, irohin ko to afojuba ni.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaseyẹ ojo na ni awọn Ọgben D. B. Olasinu, Akinogbade Oleniran, Amosun, Olawale Abiola, Salako, Adesete, Odubunmi, Adelabi, awọn Iyaafin Ọrelala, Abike Oloyede, Adeyinka ati Omidan Fadahunsi.

Aşeyışamọdun o.


No. 37.

# NOTICE

## LAGOS WATER SUPPLY

It will still be some time before any part of the new water main can be put into service and no great improvement in the supply can be expected until this is done.

Some improvement could be achieved if all waste and misuse of water was prevented and we ask for everyone's help to achieve this.

Please therefore limit your consumption to the minimum.

Please do not use a hose for watering your garden.

Please turn off any taps you see running to waste, whether in your own homes or in public places.

Please report to us any leaking taps etc. which you may see (Tel. 24846 Ext. 2). We renew washers, when necessary, free of charge.

A. P. F. TEMPLE,
Acting Engineer Manager,
Lagos Water Supply.







Eko—Opolopo awon eniа bi asofo bi alabaseye ati bi Ijo Sooşi ni o tele posi Ogbeni Emmanuel Oke Idowu Onitiri ti işe baba Ogbeni S. A. Onitiri ninu aworan ti o wa ni okee yi nigbati nwon se isin ikehin fun un tan ni Sooşi "African Cathedral (Bethel) ni Broad Street l'Eko, nwon ki o to lo sin oku re ni ite-oku Ikoyi ni ojo Aiku ti işe ojo kewa osu yi. Ologbe Onitiri je okan pataki ninu awon agba Ijo African Church o si tun je opo pataki ninu awon ti o da Ijo Africa sile ni Yaba ati Abule Oja. o si fi opolopo omo saiye lo.


*Ti idaraya nkọ o?*

*Ṣe nipa a ti gbọn eeri-inu nu ni o?*

*nję . . .*



**ta ędoki rę ji pęlu ANDREWS LIVER SAL**




Omobirin atata ni o nigbati o ba fi iyefun ANDREWS LIVER SALT ti o nia ara enia ji bere owuro ojo re! Andrews nnise larin isan-eje lati ta edoki re ji ile agbara inu ara re. O nwo inu ara lo si isale lati ran ara lowo ki o le fo ara re mo jade. Koko mu Andrews laro lojojumo, o ko si ni pe mo ohun ti ifonu yio se fun o. Awo-ara re yio ma dan-gbere pelu alafia rere ti o nti inu jade wa. O mbe laaye pelu igbadun-aiye—o si ngbadun re. O ti ni alafia koja pe ki o tun rehin lo. O si le je igbadun-aiye ni ekun rere.

RA IYỌ

**ANDREWS** alive with wake-up power!

**LIVER SALT** LONI!



NISISIYI . . . O wa fun tita ni owuwon minu lekansoso ati ninu awon agolo giomode fun asunna owo.




## *Alapara Ibadan*

**(Lati oju ewe keje)**

iya mi ati baba mi ki awon na si mo o ni oko mi ni.

Mo rora bi i lere pe titani ao ha pe oyun inu re fun awon obi re, o ni eniti alumo-nu ba wa ni owo re ni o ni i, o ni nwon igbati o je pe iwo ni wa toju mi, ma a toju mi bo pelu oyun inu mi ko si tabi-tabi nibe, iwo ni o ni oyun, sugbon ti mo ba padu si Naijiria, oloruka yo gba oruko owo, agu a di ofo o.

Mo ni o dara jeki a pa iyen ti sapakan na, se o muratan lati ba mi lo, o ni ohun ti mo le se ni ki nwa enikan ki nfi iwe ran an si on ki o dabi enipe lati Sato ni nwen ti kowe na, ki o si se sinu re pe iya on ku. ki on ma a sure bo ni kiakia nitori ninu yinyin ni nwon si gbe si, igbati mo ba de ni awon yio to sin in ki nle fi han bale mi ti nwa lodo re ki o ba le jeki mba e lo. Mo ni mo ri si yen, lola.ola yi ni ma a ko iwe na ti ma a si jeki o te o lowo, ni mo ba dagbere fun un pe o si di igbakan na.

E o ma a gbo bi a ti tun pari oro wa na si ni ose ti mbo bi Oluwa ko ba jeki a ri daasi.

# AWORAN ONITAN



# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Igbeyawo Alimi dun

Aiyegunle Gbẹdẹ lẹba Kabba

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kerin oṣu keji ọdun yi ni Ọgbẹni Alimi gbe Omidan Amina ni iyawo. Irohin ko to afojuba ni ẹyẹ iyawo na. Ọkọ iyawo fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣeyẹ igbeyawo na lọrun.

Diẹ ti a aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeyẹ na ni awọn Ọgbẹni M. O. Mejabi, S. O. Mejabi, Dare Daniel, Taiwo Abejide, Hammed Abu, Yakubu Ọlọjọ, J. F. Olowo ati A. O. Alaofin.

Ẹhin iyawo ko ni mọ ẹni, ire a kari o.

## Ọgbẹni Alao fẹ ṣe ibẹwo awọn ilu Oke-Okun kakiri.

BOLGATANGA-GHANA.

GẸGẸBI awọn Ẹgbẹ Ọmọ Shẹpẹtẹri ti o wa ni Oke-Okun ti yan Ọgbẹni E. B. Alao ninu ipade ọdun keji ti o kọja, pe ki o ma a ṣe ayẹwo awọn owo Shẹpẹtẹri kakiri awọn ilu Ghana lati mọ bi aye ti olukaluku wọn wa, nitorina yio bẹrẹ irin ajo rẹ ni ti ọdunni ni ibẹrẹ oṣu karu ọdun yi.

Awọn ilu ti yio de ni ṣiṣẹ-ntẹle lati ọjọ keji oṣu na niyi:—Naurongo, Owagadougou, Tumu, Nandom, Juna, Bole, Tamale, Gushiagu, Lungni, Kojohembo ati Walewale; yio si pari irin ajo rẹ si ilu Walewale, nigbati o ba sidi ọjọ kejilelogun oṣu kanna ni yio pada bọ wa si ibujoko iṣẹ owo rẹ ni Bolgatanga, nitorina ki olukuluku awọn ọmọ-Shẹpẹtẹri ti o ba wa ninu awọn ilu wọnyi ki o ma a mura silẹ de lati gba a ni alejo.

## Ọdẹ yinbọn pa Ọdẹ

IDAH.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni nwọn gbe ọdọmọkunrin ọdẹ kan, Ochami Ora digbadigba wa si Ile-iwosan Nla Idah, ko si pe ti nwọn gbe e de ibẹ ti o fi ku. alaye ti awọn ti o gbe e lọ sibẹ ṣe nipe, nibiti Ora ati ọdẹ ẹlẹgbẹ rẹ kan gbe nṣe ọdẹ ni ẹnikeji rẹ na ba ṣeeṣi yinbọn lu u.

## Ọmọ ẹgbẹ Olomi kan gba idaio ọgbọn pọnun fun esun eke

ILORIN.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kokanlelogbọn oṣu yi ni Ọba Ilorin Malam Sule Gambari ṣe idajo fun odaran kan baba Jimba ọmọ Ẹgbẹ Olomi (NPC) pe ki o lo fi ọgbọn pọnun tanran fun ẹsun eke ti o fi olopa Ibile kan sun pe., o gbe on ni ponun marunlelogcrun 'gbati on pelu olopa na nja. Lẹhin owo itanran yi o ni ki o tun fi ara rẹ si ọwọ fun ọdun kan.

Lẹhin na ni Ọba na tun wa ṣe idajọ pe ki odaran na ati olopa ti o baja fi pọnun meji abọ, mejiabọ tanran si kotu fun ija ti nwọn ja. Ni kotu kanna ni o tun ṣe idajo fun ọlọpa Ibile kan pe ki o fi ponun meji abọ tanran ẹsun ijongbon kan ti nwọn fi sun pe o fa.

## Irinwo obinrin nwa ọkọ ni ilu Aba

ABA.

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọgbọnjọ oṣu yi ni awọn obinrin ti ko ni ọkọ ni Abule Nteke bi irinwo enia bẹrẹ si sa sihin sa sọhun dimọ awọn ọkunrin ti ko ni aya kakiri fun abo, nigbati nwọn gbọ irọ pe Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun, fẹ ma a bu owo-ori lati san fun awon obinrin tiko ba ni ọkọ.

Awọn ọkunrin tiko ni aya paapa ati awon ti o ti ni aya bẹrẹ si pe wọn kakiri lati wa si ọdọ wọn, awon ọkunrin na si nṣe ileri fun awon obirin na pe bi nwon ba fẹ awọn, awon yio yọ won kuro ninu iberu owo-ori sisan.

Sugbon awọn ọkunrin na fi kun fun awọn obirin na pe afi bi awọn obirin wonyi ba le fe awon ni. Nigbati olori abule Nteke na gbọ irohin aifidimulẹ ti nwon ngbe kakiri ni o ba lọ ṣe ofofo fun awọn ọlọpa pe ki nwon ri si ọrọ na.

## Igi wo pa ọkunrin kan

LAFIA.

LAIPẸ yi ni nwọn ri oku ọkunrin kan, Akpiange Pev, eni ogoji ọdun ti ṣe ara TIV ninu igbẹ kan leti abule Agyaragn, ni agbegbe Lafia ni Ekun Benue. Alaye ti awon ara adugbo ibẹ ṣe nipa iku ọkunrin na ni pe, bi o ti bẹrẹsi bẹ igi ti afara-oyin wa ninu rẹ lati rẹ oyin, bi igi na si ti nwo bọ nle ni o tun fa igi miran tu, eyi ti o fatu na si wo lu u niwaju, ni o ba ku sibẹ. Ọmọ mefa ati iyawo kan ti o fẹrẹ bimọ ni ọkunrin na fi s'aiye lọ.




